# ỌGBỌ́N LATI INU IWE JOBU

**Jobu 5:17-27; 18:5-18; 14:1-22; 19:23-27; 28:1-28**

**ẸKỌ 373 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Kiyesi i; Ẹru Oluwa, eyi li ọgbọ́n, ati lati jade kuro ninu iwa-buburu eyi li oye!" (Jobu 28:28).**

**I Aabo awọn Olododo**

1 A o gba a la kuro ninu ipọnju gbogbo, Jobu 5:17-22; Orin Dafidi 103:3, 4

2 Oun yoo wà ni alaafia pẹlu awọn ẹda, Jobu 5:23, 24; Isaiah 55:12

3 A o fa ọjọ́ ayé rẹ̀ gùn, Jobu 5:25-27; Orin Dafidi 91:16; Owe 3:2

**II Iparun awọn Eniyan Buburu**

1 Fitila rẹ̀ ni a o pa, Jobu 18:5, 6; Matteu 8:12

2 Imọ̀ oun tikara rẹ̀ ni yoo bi i ṣubu, Jobu 18:7, 8; Owe 3:5

3 Yoo maa buru fun un siwaju ati siwaju, Jobu 18:9-18

**III Ajinde Kuro ninu Oku**

1 Ayé ti a wà yii kuru, Jobu 14:1-6, 10-13; Jakọbu 4:14; 1 Peteru 1:24

2 A ri apẹẹrẹ ajinde ninu awọn ẹda, Jobu 14:7-9; 1 Kọrinti 15:36-38

3 Jobu ni idaniloju pe oun yoo jinde, Jobu 14:14, 15; 19:23-27

4 A ti dari ẹ̀ṣẹ Jobu atẹyinwa ji i, Jobu 14:16, 17; Orin Dafidi 32:1

5 A ri ikú ati idibajẹ ti o wà ninu eniyan ati awọn ẹda, Jobu 14:18-22

**IV Ipo Ọgbọ́n**

1 Eniyan kò ri ọgbọ́n ninu ilepa rẹ̀ fun ọrọ̀, Jobu 28:1-12

2 Eniyan kò le fi ọrọ̀ rẹ̀ ra a, Jobu 28:13-21

3 Ọlọrun mọ ipò ọgbọ́n, Jobu 28:22-27; Oniwasu 2:26

4 Ọlọrun paṣẹ fun eniyan lati bẹru Oun ati lati jade kuro ninu iwa buburu, Jobu 28:28; Oniwasu 12:13, 14

## ALAYE

### A Pa Awọn Eniyan Buburu Run; A si Daabò Bo Awọn Olododo

"Ọ̀pọlọpọ ni ipọnju olododo; ṣugbọn OLUWA gbà a ninu wọn gbogbo" (Orin Dafidi 34:19). A dán Jobu wò dé ogogoro ninu ipọnju rẹ̀; to bẹẹ ti awọn ọrẹ rẹ̀ fi rò pé dajudaju o ni lati jẹ pe o ti dẹṣẹ buburu kan ni. Ero Elifasi ni pe bi o ba ṣe pe Jobu jẹ́ olododo ni, a o gbà á kuro ninu gbogbo iyọnu rẹ̀. Bi o tilẹ jẹ pe ohun ti Elifasi sọ nipa Jobu ki i ṣe ootọ sibẹ ohun ti o sọ nipa aabo Ọlọrun fun awọn eniyan rẹ jẹ otitọ: "Ninu iyan yio gbà ọ lọwọ ikú, ati ninu ogun yio gbà ọ lọwọ idà" (Jobu 5:20). "Nitoripe iwọ o ba okuta igbẹ mulẹ̀, awọn ẹranko igbẹ yio wà pẹlu rẹ li alafia" (Jobu 5:23).

Gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ ti ba alaafia ti o wà ninu Ọgba Edẹni jẹ́, bakan naa ni ẹ̀ṣẹ lode oni n fi ọtá saarin eniyan ati eto ilana ẹda. Lọna kin-in-ni, o ba irẹpọ ti o wà laaarin eniyan ati Ẹlẹda rẹ̀ jẹ́. Iwa ẹ̀ṣẹ ti du eniyan ni igbesi-ayé alaafia ati ilera. Tábà mimu maa n mú àrun jẹdọjẹdọ wá. Ere idaraya, wiwo ẹ̀rọ amohun-maworan pẹlu ijo jijo ti mú ki ifẹkufẹ dagba soke, eyi ni o si mú ki ọ̀pọlọpọ ile fọ́. Mimu ọti ati ohun oloro gbogbo maa n sọ eniyan di eniyan-keniyan ati ẹni ti kò wulo. "Ẹ̀ru nla yio bà a … Ailera rẹ̀ yio di pipa fun ebi … Eyi ti o fi gbẹkẹle ni a o fàtu kuro … Gbongbo rẹ̀ yio gbẹ nisalẹ, a o si ké ẹ̀ka rẹ̀ kuro loke … A o si le e lati inu imọlẹ sinu òkunkun, a o si le e kuro li aiye" (Jobu 18:11-18).

Nigba ti "ọba ẹ̀ru nla" (Jobu 18:14) ba n tọpasẹ eniyan ibi lojoojumọ, Oluwa "ki imu oju rẹ̀ kuro lara olododo" (Jobu 36:7). "Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ Kristi? ipọnju ni, tabi wahalà, tabi inunibini, tabi ìyan, tabi ihoho, tabi ewu, tabi idà? …Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa jù ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa" (Romu 8:35-37).

Ọlọrun rán iyàn si Israẹli nitori ẹ̀ṣẹ wọn, ṣugbọn O rán awọn ẹyẹ iwò lati maa bọ́ Elijah wolii Rẹ̀. Nigba ti ahọn awọn eniyan buburu ditẹ lati pa Daniẹli run; Ọlọrun gba a kuro ninu iho awọn kiniun. Ọlọrun daabo bo Noa nigba ti a pa gbogbo ayé run, O si mú ki o gbé ni alaafia ninu ọkọ̀ pẹlu awọn ẹranko ìgbẹ́ ni oriṣiriṣi ẹ̀ya wọn. Dajudaju a fi idi rẹ mulẹ pe, "Ninu iyàn yio gbà ọ lọwọ ikú, ati ninu ogun yio gbà ọ lọwọ idà. A o pa ọ mọ kuro lọwọ ina ahọn: bẽni iwọ ki yio bẹ̀ru iparun nigbati o ba dé … bẽni iwọ ki yio bẹ̀ru ẹranko ilẹ aiye" (Jobu 5:20-22).

**Ajinde**

Bi a tilẹ fi Jobu sùn pé agabagebe ni, o mọ̀ daju pe kukuru ni ayé yii ati nipa ẹmi ọmọ eniyan ti ki i kú. Jobu beere pe, "Nitoripe kini ireti àgabagebe, (bi o tilẹ jere) nigbati Ọlọrun ba ke ẹmi rẹ̀ kuro" (Jobu 27:8). "Enia ti a bi ninu obirin ọlọjọ diẹ ni … O jade wá bi itanna eweko, a si ke e lulẹ" (Jobu 14:1, 2). Jobu ṣe akiyesi pe: "Nitoripe abá wà fun igi, bi a ba ke e lulẹ, pe yio si tun sọ … Bi gbongbo rẹ̀ tilẹ di ogbó ninu ilẹ ti kukute rẹ̀ si kú ni ilẹ. Sibẹ nigbati o ba gbõrùn omi, yio sọ … Ṣugbọn enia kú,… on ha da?" (Jobu 14:7-10). Ninu akiyesi rẹ̀ kò ti si eniyan ti o ti inu isa-oku jade. Ṣugbọn nigba ti o beere pe, "Bi enia ba kú yio si tun yè bi?" Ọkàn rẹ̀ fesi bayii pe, "Gbogbo ọjọ igba ti a là silẹ fun mi li emi o duro dè, titi amudọtun mi yio fi de. Iwọ iba pè, emi iba si da ọ lohun" (Jobu 14:14, 15).

Bi Jobu ti n ṣe aṣaro lori ọrọ yii bẹẹ ni idaniloju rẹ̀ n pọ̀ si i, titi o fi ké pé, "A! Ibaṣepe a le kọwe ọrọ mi nisisiyi, ibaṣepe a le dà a sinu iwe! … Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi mbẹ li ãyè, ati pe on bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ. Ati lẹhin igba awọ ara mi, ti a ti ke e kuro bi iru eyi, ati laili ẹran-ara mi li emi o ri Ọlọrun: Ẹniti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o si wò, ki si iṣe ti ẹlomiran; ọkàn mi si dáku ni inu mi" (Jobu 19:23-27). Igbagbọ́ Jobu kò duro lori aileku ẹmi nikan, ṣugbọn ó ni igbagbọ́ ninu ajinde ara. O sọ asọtẹlẹ nipa Ijọba Kristi ni ayé nigba ti o wi bayii pe "On bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ .. ti oju mi o si wò, ki si iṣe ti ẹlomiran."

**Ilepa Fun Ọgbọ́n**

"Ṣugbọn nibo li a o gbe wá ọgbọ́n ri, nibo si ni ibi oye?" (Jobu 28:12). Ninu ṣiṣe ayẹwo ibeere yii, Jobu fiyesi i pe, fadaka, wura, irin, idẹ ati safiri, gbogbo wọn ni o ni ipò wọn. Eniyan maa n wá wọn ri nipa wiwa abẹ́ oke nla ati rirá wọ ibi ti "oju gunnugun kò ri i ri" ati nibi ti kiniun kò rin ri. "O si mu ohun ti o lumọ hàn jade wá si imọlẹ," o wà a jade lati inu okunkun labẹ ilẹ.

Ọpọlọpọ okuta iyebiye ni eniyan ti ṣe awari, nipa lilọ si abẹ apata nla: ṣugbọn nibi ti ọgbọ́n wa, "ọgbun wipe, kò si ninu mi." Eniyan a maa mookùn ninu òkun lati wá okuta perli ri, ṣugbọn òkun wi pe, "kò si ninu mi." Eniyan pẹlu agbára rẹ̀ ati ilepa rẹ̀ ojoojumọ fun awọn ohun alumọni kò i ti wá ibi ti ọgbọ́n wà ri.

Gbogbo ohun alumọni ti eniyan ti kó jọ, bi o ti wu ki o niye lori tó, kò le fi ra ọgbọ́n. "A kò le fi wurà rà a, bẽli a kò le ifi òṣuwọn wọ̀n fadaka ni iye rẹ̀" (Jobu 28:15). "Nibo ha li ọgbọ́n ti jade wá, tabi nibo ni ibi oye?" (Jobu 28:20). Eniyan kò ri i ninu òkun tabi lori ilẹ, tabi labẹ ilẹ, tabi ninu afẹfẹ. "Ibi iparun (Abaddoni) ati ikú wipe, Awa ti fi etí wa gburo rẹ̀." Ṣugbọn wọn kò i ti ṣe awari ibi ti ọgbọ́n wà.

Idahun si ilepa ọgbọ́n ni eyi "Ọlọrun li o moye ipa ọ̀na rẹ̀, o si mọ̀ ipo rẹ̀. Nitoripe o woye de opin aiye, o si ri gbogbo isalẹ ọrun" (Jobu 28:23, 24). Pẹlu gbogbo ẹ̀rọ iworan ti eniyan le ni diẹ ni ibi ti o le ri, ṣugbọn oju Ọlọrun n wo ibi gbogbo pẹlu titan manamana Rẹ̀. "Nigbana li o ri i, o si sọ ọ jade, o pèse rẹ̀ silẹ, ani o si wadi rẹ̀ ri" (Jobu 28:27). Nigba naa ni Ọlọrun yi pada si eniyan, O si wi fun un pe: "Kiyesi i; Ẹru Oluwa, eyi li ọgbọ́n, ati lati jade kuro ninu iwa-buburu eyi li oye!" (Jobu 28:28). Lẹyin ti Sọlomọni ọkunrin ti o lọgbọ́n ju lọ ti wo gbogbo igbesi-ayé eniyan o pari gbogbo rẹ̀ ni ọ̀rọ bayii pe: "Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia. Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ikọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu" (Oniwasu 12:13, 14).

**AWỌN IBEERE**

1 Darukọ diẹ ninu awọn iyọnu ti Ọlọrun n yọ awọn olododo kuro ninu rẹ̀, ki o si sọ apẹẹrẹ lati inu Bibeli irú awọn ti a yọ bẹẹ.

2 Ki ni itumọ ọ̀rọ yii pe ki a bá okuta igbẹ́ mulẹ̀?

3 Sọ diẹ ninu awọn nnkan ti o n ṣẹlẹ si awọn eniyan buburu (Jobu 18).

4 Ki ni Bibeli fi igbesi-ayé kukuru eniyan wé? Fi Bibeli gbè é lẹsẹ.

5 Sọ awọn nnkan wọnni ti n ṣẹlẹ si ẹdá ti o fi ẹsẹ ajinde mulẹ.

6 Jobu wi bayii pe: "Titi amudọtun mi yio fi de" (Jobu 14:14). Ki ni itumọ rẹ̀?

7 Ki ni apẹẹrẹ ti o fi hàn pe Jobu ni igbagbọ́ ninu ajinde ara?

8 Ki ni asọtẹlẹ Jobu nipa bibọ̀ Kristi lẹẹkeji?

9 Ki ni eniyan kuna lati wá ri ninu ilepa rẹ̀ fun awọn ohun ti o ṣe iyebiye?

10 Ki ni ọgbọ́n?